# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ̀

## ẸBỌ TÓ GA JÙ

### Ìtàn ...

**Genesis 22:1-19**

Òkùnkùn sì kùn nígbàtí baba wa àgbà gbọ́ ohùn Ọlọrun kedere wípé; "Abrahamu, mú ọmọ rẹ nísinsìnyìí, Isaaki, ọmọ rẹ nàá kansoso, tí ìwọ fẹ́, kí ìwọ kí o sì lọ sí ilẹ̀ Moria; kí o sì fi rúbọ sísun níbẹ̀ lórí ọ̀kan nínú òkè tí èmi ó sọ fún ọ." Genesisi 22:1,2.

Abrahamu sì bẹ̀rẹ̀ sí i dààmú nígbàtí ó rò abajade àṣẹ yìí. Ọlọrun ti ṣe ìlérí wípé nípasẹ̀ Isaaki ni yio di baba orílẹ̀-èdè alágbára. Gbogbo ìrètí Abrahamu ati àlá rẹ̀ ni o fi gbẹ́kẹ̀lé ọmọ ìyanu ti a fi fún un ati Sara ni ọjọ́ ogbó wọn. Kò mo ìdí tí Ọlọrun fi sọ fún un wípé kí ó gbé irú ìgbésẹ̀ bí èyí, ṣùgbọ́n ó ti kọ́ àti maa gbẹ́kẹ̀le àti lati gbọ́ràn sí Baba rẹ̀ ọ̀run lẹ́nu – bí o tilẹ̀ wà nínú iporuru ọkan.


©Review and Herald

Nítorí náà, Abrahamu rọra jí Isaaki ati ọ̀dọ́mọkunrin rẹ̀ mejì ti ó gba ẹrí wọn jẹ́, bẹ́ẹ̀ni àwon ẹgbẹ kékeré yi bẹ̀rẹ̀ ìrìn àjò ọlọ́jọ́ mẹta wọn sí Moria. Bí wọn ti dé ìtòsí òkè írúbo, Abrahamu sì wí fún àwon ọdọmọkunrin rẹ̀ pé kí wọn dúró de oun, ṣùgbọ́n oun àti Isaaki yio lọ sí ọ̀hún nì, àwa yio sì tún padà tọ̀ yín wá. Bẹ́ẹ̀ni ó mú igi ẹbọ sísun náà, o di i ru Isaaki ọmọ rẹ̀, wọn sì jọ gun òkè lọ.

Isaaki rí wípé ohun èlò ẹbọ kò pé, nítorí náà o wípé, "Baba, Wo iná oun igi; ṣùgbọ́n níbo li ọ̀dọ́-agutan ẹbọ náà gbé wà? Abrahamu sì wípé, "Ọmọ mi, Ọlọrun tikalarẹ̀ ni yio pèsè ọ̀dọ́-agutan fun ẹbọ sísun."

Bí wọn sì ti dé òkè, Abrahamu fi tẹkún-tẹkún ṣe àlàyé pàtàkì ìrìn-àjò wọn. Lati ọkàn wá Isaaki jọ̀wọ́ ara rẹ̀ fun àṣẹ Ọlọrun. Lẹhin ìgbàtí wọn dì mọra wọn tán, baba rẹ̀ rọra di ọmọ rẹ̀, o sì gbé e lé ori òkuta ìrúbọ náà. Abrahamu sì gbé ọ̀bẹ sókè, ṣùgbọ́n a dá a dúró nípasẹ̀ angẹli kan, a sì wí fún un wípé kí ó fi àgbò kan ti o fi iwo rẹ̀ há ni pantiri se ìrúbo náà ni ipò ọmọ rẹ̀.

Ìtàn tó mi ènìyàn yi kọ́ ni ìgbà àkọ́kọ́ tí baba yíò gbé irú ìgbésẹ̀ tó roni lára lati fi ọmọ rẹ̀ kan soso rúbọ.

AMAZING FACTS

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Tani ẹranko tí a fi ṣe ìrúbo ni ipò Isaaki dúró fún?
**John 1:29**
Ni ijọ keji Johannu rí ________ mbọ̀ wá sọ́dọ̀ rẹ; o wípé, Wò ó,___ _______ Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ̀ ayé lọ.

2. Kinni ìdí ti o fi ṣe pàtàkì fún Jesu lati kú?
**Romu 3:23**
_______ ènìyàn li o sa ti ṣẹ̀, ti nwọn sì kùnà ogo Ọlọrun.
**Romu 6:23**
Nítorí _____ li èrè ẹ̀ṣẹ̀; ṣùgbọ́n ẹ̀bùn ọ̀fẹ́ Ọlọrun ni ìyè tí kò nípẹ̀kun, nínú Kristi Jesu Oluwa wa.
**Heberu 9:22**
O sì fẹrẹ jẹ́ ohun gbogbo li a fi ẹ̀jẹ̀ wẹ̀nù gẹ́gẹ́ bi ọ̀fin; àti láìsí __________ kò sí ìdáríjì.
**1 Korinti 15:3**
Nítorí pé síwájú ohun gbogbo mo fi èyítí èmi pẹ̀lú ti gbà le nyin lọ́wọ́, bi Kristi ti kú nítorí _____ wa gẹ́gẹ́ bí ìwé mímọ́ ti wí.
**1 Peteru 3:18**
Nítorí tí Kristi pẹ̀lú jìyà lẹ̀ẹ̀kan nítorí ẹ̀ṣẹ̀ wa, ________ fún àwọn _________, ki o le mú wa de ọ̀dọ̀ Ọlọrun, ẹnití a pa nínú ara, ṣùgbọ́n tí a sọ di ààyè nínú ẹ̀mí.

Àkíyèsí: A kò le è sọ iye tí Bibeli tó nítorí o sọ fún wa bi ẹ̀ṣẹ̀ ṣe wọ ayé àti bi a o ṣe mú u kúrò. Ọlọrun kò le faramọ ìrira ẹ̀ṣẹ̀. Ikú li èrè ẹ̀ṣẹ̀. Èyi to tún burujù, nígbatí Adamu àti Efa dẹ́ṣẹ̀, ààrùn ikú yi kọjá sórí gbogbo ìran ènìyàn. Òfin Ọlọrun àti ìjìyà fún ríré òfin kọjá ko lee ṣe é yí padà, nítorí náà gbogbo ènìyàn ṣẹ̀gbé. Ṣùgbọ́n Ọlọrun kò le e dúró lati ya ara Rẹ̀ kúrò lára àwon iṣẹ̀ ọwọ́ Rẹ̀. Nírorí náà, nínú ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́ O yàn lati rán Ọmọ Rẹ̀ sí inú ayé lati kú ní ipò tìrẹ ati ti èmi. Ìjìyà ẹ̀ṣẹ̀ àti ikú wa ni a dì le e li orí, a si tú wa sílẹ̀.

3. Kinni orúkọ ti ètò ìgbàlà tó ga yi njẹ́?
**Ifihan 14:6**
Mo sì rí angẹli miran nfo li agbedemeji ọ̀run, ti oun ìí __________ àìnípẹ̀kun lati waasu fún àwọn ti ngbé orí ilẹ̀ ayé ati fún gbogbo orilẹ̀, ati ẹ̀yà, ati èdè, àti ènìyàn.

Àkíyèsí: ÈTÒ ìgbàlà Ọlọrun ni a n pè ní "ìhìnrere" èyí ti o tumọ sí "ìròhìn rere". Àti ni òtítọ́, o jẹ́ ìtàn tí ó lágbára ti a le sọ fún ènìyàn. Ìjìyà ikú wa li Jesu ti gbà jẹ, a sì mu ìdálẹbi wa kúrò.

4. Kinni idi ti Ọlọrun fi se irú ẹbọ iyebíye yi fún wa?
**Johannu 3:16**
Nítorí Ọlọrun _____ aráyé to bẹ̀ẹ̀ gẹ́, tí o fi ọmọ bibi rẹ̀ kan soso _______, ki ẹnikẹni ti o ba gbà á gbọ́ ma ba ṣègbé, ṣùgbọ́n kí o le ni ìyè àìnípẹ̀kun.

Àkíyèsí: Okùn tó lágbára jù li ayé ni ìfẹ́ tí òbí ní sí ọmọ rẹ̀. Nígbàtí Ọlọrun Baba fẹ́ lati fun wa ni Ọmọ Rẹ̀, Jesu, ti o jìyà ti o sì kú ni ipò wa, O fihàn ninu èdè tó lágbàra bi Oun se fẹ́ràn wa tó.





5. Kinni mo gbọ́dọ̀ ṣe lati jẹ́ ànfàànì nínú ikú ti Jesu fi ṣe ìrúbọ fun wa?
**Ise Awọn Aposteli 16:31**
Nwọn sì wí fún un pé, Gba Jesu Kristi Oluwa ______, a o si gbà ọ là ìwọ àti àwon ara ilé rẹ pẹ̀lú.
**Johannu 1:12**
Ṣùgbọ́n iye àwọn ti o gbà á, àwọn li o fi agbára fún lati di _________ ________, àní àwọn naa ti o gba orúkọ rẹ̀ gbọ́.

Àkíyèsí: Ìrúbọ tí Jesu ṣe fún ìgbàlà jẹ́ ẹ̀bùn (Romu 6:23). Ipa temi ni lati gbàgbọ́ pé òtítọ́ ni àti pé ki nsì gbà ẹ̀bùn náà nípa ìgbàgbọ́.

6. Báwo ni mo ṣe rí ìdáríjì gbà àti pé báwo ni mo ṣe di mímọ́?
**Ise Awọn Aposteli 3:19**
Nítorí náà ẹ ___________, kí ẹ sì tún yípadà, ki a lè pa ẹ̀ṣẹ̀ nyin rẹ́, kí àkókò ìtura ba le ti iwájú Oluwa wá.
**1 Johannu 1:9**
Bí àwa ba ______ ẹ̀ṣẹ̀ wa, olóotọ ati olódodo li oun lati dárí ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá, àti lati ______ wá nù kúrò ninu àìsododo gbogbo.

Àkíyèsí: Ìjẹ́wọ́ ni síso ọ̀rọ̀ ní ìgbà ìrònúpìwàdà. Ìrònúpìwàdà tòótọ́ jẹ́ ìbànújẹ́ fun - ati yíyípadà kúrò nínú – ẹ̀ṣẹ̀ (Owe 28:13).

7. Kinni orúkọ ti ìrírí íyípadà ìyanu yi njẹ́?
**Johannu 3:7**
Kí ẹnu kí o maṣe yà ọ́, nítorí mo wí fún ọ pé, A kò le ṣe aláìtún nyin ________.

Àkíyèsí: Ìrírí ológo yi ntọ́ka sí ìbí titun nítorí, ní ìkórita náà, a kò ní ìgbé ayé to ti kọjá. Dipo bẹ́ẹ̀, a ó bẹ̀rẹ̀ ìgbé ayé titun, gẹ́gẹ́ bi ọmọ titun tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ bí. Ó jẹ́ ìrírí ìyanu pé a bẹ̀rẹ̀ ìgbé ayé titun láìní ìdálẹbi kankan nínú àkosílẹ̀ wa.

8. Tani o ma nwọ inú ọkàn àwon àtúnbí Kristiani?
**Johannu 14:17**
Àní _________ òtítọ́ nì; ẹnití aráyé kò le gbà, nítorí tí kò ri i, bẹ́ẹ̀ni kò sì mọ̀ ọ́n: ṣùgbọ́n ẹnyin mọ̀ ọ́n; nítorí tí o mba nyin gbé, yio sì wà nínú nyin.

Àkíyèsí: Dájúdájú Jesu funrararẹ̀ ngbé inú Kristiani nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́.

9. Nígbàtí Jesu ngbé inú ọkàn mi nipase Ẹ̀mí Mímọ́, kinni n o ṣe?
**Filippi 2:13**
Nítorí pé Ọlọrun ni nsiṣẹ́ nínú nyin, lati fẹ́ àti lati _________ fún ìfẹ́ inú rere rẹ̀.

Àkíyèsí: Ma a fẹ́ lati ṣe ìfe Rẹ̀, yí Ó sì fún mi lágbàra lati ṣe bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́.

10. Kíni ìdí tí mo fi gbọ́dọ̀ ní ìgboyà wípé ìrírí àtúnbí mi yio yege?
**Filippi 1:6**
Ohun kan yi sa dá mi lójú, pé ẹnití o ti __________ iṣẹ́ rere ninu nyin, yio ṣe àṣepé rẹ̀ títí fi di ọjọ́ Jesu Kristi.

Àkíyèsí: Mo ni ìgboya nítorí Jesu ti ṣe ìlérí àti lati mú u ṣe fúnmi pẹ̀lú agbára nlá Rẹ̀. Ìgbàlà sinmi lori ipá Rẹ̀, ki iṣe tèmi.



YOR-SP5.indd 1
12/6/12 10:42 AM

**11.** Kíni ìdí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ fi nkùnà nínú ìrírí Kristiani wọn?

**Isaiah 53:6**
Gbogbo wa ti sìnà kirikiri bi agutan, olukuluku wa tẹle ________ ara ______; OLUWA sì ti mu aisedeede wa gbogbo pade lara rẹ.

**2 Peteru 3:2**
Kí ẹnyin ki o lè máa ránti ọ̀rọ̀ ti a ti ẹnu àwon woli mímọ́ sọ sáájú, àti òfin _________ ati Olugbala wa lati ọ̀dọ̀ àwon aposteli nyin.

Àkíyèsí: Àwọn ènìyàn má nkùnà nínú ìgbé ayé Kristiani wọn, nítorí wípé wọn gba Jesu li Olugbala,ṣùgbọ́n wọn kò gbà A ní Oluwa, tàbi 'aláṣẹ' lórí ayé wọn. Púpọ̀ nínu wa fẹ́ lati ní ọ̀nà ara rẹ̀ àti pé kí a sì má a gbé ìgbé-ayé wa bí o ṣe wù wa. Bí a ba gba Jesu li Oluwa wa, a o gbé ayé wa lé E lọ́wọ́, kí Ó lè má a ṣe àkóso rẹ̀. A o gbe ọwọ́ kúrò lára ọkọ̀ ayé wa, a ó sì pè É láti má a dári wa. (Wo àfikún "Ìgbàlà lẹ́ẹ̀kan, Ìgbàlà ní ìgbà gbogbo")

**12.** Báwo ni n o ṣe mọ̀ wípé Jesu ti gbàmí àti wípé mo jẹ́ ọmọ Rẹ̀?

**Titu 1:2**
Ní ìrètí ìyè àìnípẹkun, tí Ọlọrun, Ẹnití kò le ṣèké, ti ṣe ______ ṣáájú ìpilẹ̀ṣẹ̀ ayé.

**Matteu 7:7**
Bèrè, a ó _______ fi fún nyín; wá kiri, ẹnyin o sì ri; kànkùn, a ó sì sí i sílẹ̀ fún nyin.

Àkíyèsí: A mọ̀ wípé Jesu ngbà wa nígbàtí a bá bèrè lọ́wọ́ Rẹ̀, nítorí wípé kò lee parọ́. O ti ṣèlérí lati gbà wá, O si ngbà wá – ki i ṣe tìtoríṕé a rò pé a yàtọ̀, ṣùgbọ́n nítorí wípé O ti ṣèlérí.

**13.** Báwo ni ìyípadà tòótọ́ yio ṣe yí ayé padà?

(a) **Johannu 13:35**
Nípa èyí ni gbogbo ènìyàn yio fi mọ̀ pé, ọmọ-ẹhin mi li ẹnyin iṣe, nígbàtí ẹnyin ba ní _______ sí ọmọnikeji nyin.

(b) **2 Korinti 5:17**
Nítorí náà bí ẹnikẹni bá wà nínú Kristi, o di ẹ̀dá _______: ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; kíyèsi i, nwọn si di titun.

(d) **1 Johannu 3:22**
Àti ohunkóhun ti àwa ba bèrè, àwa nrí gbà lọ́dọ̀ rẹ̀, nítorí tí àwa npa òfin rẹ̀ mọ́, awa si ______ nkan wọnni tí o dára lójú rẹ̀.

(e) **Romu 12:2**
Ki ẹ ma sì da ara nyin pọ̀ mọ _____ yi: ṣùgbọ́n kí ẹ _________ lati di titun ni ìrò-inú nyin, ki ẹnyin ki o le ri ìdí ______ Ọlọrun, tí o dára, ti o si ṣe ìtẹ́wọ́gbà, ti o si pé.

(ẹ) **Ise Awọn Aposteli 1:8**
Ṣùgbọ́n ẹnyin o gba agbára, nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bá bà le nyin: ẹ o sì ma ṣe __________ mi ni jerusalemu, ati ni gbogbo Judea, ati ni Samaria, ati títí dé òpin ilẹ̀ ayé.

(f) **Efesu 6:18**
Pẹ̀lú gbogbo __________ àti ẹ̀bẹ̀ ni ki ẹ maa gbàdúrà nígbà gbogbo nínú Ẹ̀mí, kí ẹ sì máa sọ́ra si i nínú ìdúró ṣinṣin gbogbo, ati ẹ̀bẹ̀ fún gbogbo ènìyàn mímọ́.

**14.** Kínni ìlérí ìyanu tí ó wá pẹ̀lú ìgbé ayé Kristiani?

(a) **Filippi 4:13**
Emi le ṣe _________ ___________ nínú Kristi ẹniti nfi agbára fún mi.



(b) **Filippi 4:19**
Ṣùgbọ́n Ọlọrun mi yio pèsè ní kíkún fún gbogbo ________ nyin, gẹ́gẹ́ bi orọ̀ rẹ̀ ninu ògo nínu Kristi Jesu.

(d) **Marku 10:27**
Jesu sì wò wọn ó wípé, Ènìyàn li èyi kò le ṣe iṣe fún, ṣùgbọ́n ki iṣe fún Ọlọrun: nítorí ohun gbogbo ni ________ fún Ọlọrun.

(e) **Johannu 15:11**
Nkan wọnyi ni mo ti sọ fún nyin, ki ayọ̀ mi ki o lè wà nínú nyin, àti ki ______ nyin ki o le kún.

(ẹ) **Johannu 10:10**
Olè kì íwá bí kò ṣe lati jalè, àti lati pa, àti lati parun: emi wa ki nwọn le ni ìyè, àní kí nwọn le ní in ___________.

(f) **Heberu 13:5**
Ki ọkàn nyin kí o maṣe fà sí ìfẹ́ owó, kí ohun tí ẹ ní kí o to nyin; nítorí oun tikararẹ̀ ti wípé, Emi kò jẹ́ fi ọ ________, bẹ́ẹ̀ni emi ko jẹ́ kọ̀ ọ́ sílẹ̀.

(g) **Heberu 13:6**
Nítorí náà ni awa ṣe nfi ìgboyà wípé, Oluwa li olùrànlọ́wọ́ mi, emi ki yio ________; kíli ènìyàn le ṣe sí mi.

(gb) **Johannu 14:27**
__________ ni mo fi sílẹ̀ fun nyin, alaafia mi ni mo fi fún nyin: ki iṣe gẹ́gẹ́ bí ayé iti fi fun ni li emi fi fun nyin. Ẹ maṣe jẹ́ kí ọkàn nyin dàrú, ẹ má sì jẹ́ kí ó wárìrì.

Àkíyèsí: Ọlọrun fún àwọn ènìyàn Rẹ̀ li ìlérí méje tí o ṣe iyebíye yii:

- A le e ní ohunkohun nípaṣẹ Jesu.
- Gbogbo àìní wa ni a o pèsè fun.
- Kò sí ohun tí kò li lee se é ṣe fún wa.
- Ayọ̀ wa yio di kíkún.
- A o ní ìyè lọ́pọ̀lọpọ̀.
- Ọlọrun kò ní fi wa sílẹ̀ tàbí kọ wá sílẹ̀.
- A kò gbọdọ̀ bẹ̀rù ohun ti ènìyàn yio ṣe si wa.

Oluwa yio fún wa ni alaafia pípé Rẹ̀. Ẹ yin Oluwa lógo! Bawo ni ohun kan yio ṣe dára jù èyí lọ?

# Èsì Rẹ

Se iwọ yio gbé ìgbésẹ̀ lati gba ètò Jesu lati gbà ọ, tabi o fẹ́ tún ìgbésẹ̀ náà ṣe lọtun?

ÌDÁHÙN: ________________

# Àfikún

Ipele yii pèsè àwon ìròhìn àfikún fún ikẹkọ tẹ̀síwájú.

Ṣe Ìgbàlà lẹ́ẹ̀kan ni Ìgbàlà ní gbogbo ìgbà?

Ṣe ènìyàn kan tún le è ṣọnu lẹ́hìn ìgbà to ti gba Jesu gẹ́gẹ́ bi Olugbala? Nínú ọ̀rọ̀ Ọlọrun nìkan li a ti le e rí ìdáhùn sí ìbéèrè yii. Bibeli funrararẹ sọ pé: "Ẹ jẹ́ kí a di ìjẹ́wọ́ ìrètí wa mu ṣinṣin li aiṣiyemeji; (nitori pé olootọ li ẹniti o ṣe ileri;) Ẹ jẹ́ ki a yẹ ara wa wò lati rú ara wa sí ìfẹ́ ati sí iṣẹ́ rere. ... Nítorí bí awa ba mọnmọ̀ dẹ́ṣẹ̀ lẹhin ìgbàtí awa ba ti gbà imọ̀ òtítọ́ kò tún sí ẹbọ fún ẹ̀ṣẹ̀ mọ́." Heberu 10:23,24,26.



Kò sí ibi tí Bibeli tí sọ fún wa wípé ojuṣe wa ti parí bí a ba ti di Kristiani. Ọ̀rọ̀ Ọlọrun ṣe tààrà: "Nítorí lẹhìn ti nwọn bá ti yọ tán kúrò nínú èérí ayé, nípa mímọ̀ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi, bi nwọn bá sì tún fi ara kó o, ti a sì ṣẹgun wọn, ìgbẹ̀hìn wọn a burú ju ti ìṣáájú lọ, Nítorí iba sàn fún wọn, ki nwọn ki o ma mọ̀ ọ̀nà òdodo, ju lẹhin ti nwọn mọ̀ ọn tán, kí nwọn kí o yípadà kúrò ninu òfin mímọ́ tí a fi fun wọn, Òwe òtítọ́ nì ṣẹ sí wọn lára, Ajá tún padà sí èébì ara rẹ̀; àti ẹlẹ́dẹ̀ tí a ti wẹ̀ mọ́ sínú àfọ̀ ninu ẹrẹ̀." 2 Peteru 2:20-23.

Ìgbé ayé Kristiani ju ìgbésẹ̀ kan lọ. Jesu sọ wípé ìgbàlà wa dúró lórí gbèdéke wípé kí a má a tẹ̀síwájú lati má a gbé inú Rẹ̀ (Johannu 15:4). Aposteli Paulu sọ wípé, "Emi nkú lójoojúmọ́." (1 Korinti 15:31). Èyí túmọ̀ sí wípé, o yàn lójoojúmọ́ lati má a sẹ́ ara rẹ̀ àti lati má a tẹ̀lé Jesu. Oluwa tikalarẹ̀ sọ wípé, "Bi ẹnìkan ba nfẹ́ lati máa tọ̀ mí lẹ́hìn, kí ó sẹ́ ara rẹ̀, kí ó sì gbé àgbélèbú rẹ̀ ní ijọ́ gbogbo, kí ó sì máa tọ̀ mí lẹ́hìn. Luku 9:23.

Bibeli kò kọ wa pé, a le kọ ẹ̀hìn sí òtítọ́ kí a sì tún di ẹni ìgbàlà nípa bẹ́ẹ̀. Ezekieli 18:24 sọ wípé: "Ṣùgbọ́n nígbàtí olododo bá yípadà kúrò nínú òdodo rẹ̀, tí ó sì hùwà àìṣedéédé, tí o si ṣe gẹ́gẹ́ bi gbogbo ìrira ti ènìyan búburú nṣe, oun o ha yè? Gbogbo òdodo rẹ̀ tí o ti ṣe ni a kì yio rántí: nínú ìrékọjá rẹ̀ tí o ti ṣe, àti nínú ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ tí o ti dá, nínú wọn ni yio kú." Paulu si tún rán wa létí, ''Nítorí náà ẹnití o ba rò pé oun dúró, kí ó kíyèsara, ki o ma ba ṣubú." 1 Korinti 10:12.

Ọ̀pọ̀ ènìyàn rò wípé àwọn le e "sọ̀rọ̀, sọ̀rọ̀ náà" lí àìṣepé wọn "rìn ìrìn náà". Ṣùgbọ́n Jesu sọ wípé: "Kì íṣe gbogbo ẹniti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio wọle ìjọba ọrun; bíkòṣe ẹniti nṣe ìfẹ́ ti Baba mi ti mbẹ li ọrun, Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni yio wí fún mi li ọjọ́ náà pé, Oluwa, Oluwa, àwa ko ha sọtẹlẹ li oruko rẹ? ati orukọ rẹ ki a fi lé àwọn ẹmí èṣù jade? àti li orúkọ rẹ kí a fi ṣe ọ̀pọ̀ iṣẹ́ ìyanu nlá? Nígbà náà li èmi ó sì jẹ́wọ́ wí fún wọn pé, Emi kò mọ̀ nyin rí, ẹ kúrò lọdọ mi ẹnyin oníṣẹ ẹ̀ṣẹ̀. Matteu 7:21-23.

Paulu sọ̀rọ̀ nípa ìjàkadì ìgbà gbogbo ti Kristiani òtítọ́ nígbàtí ó wípé: "Ẹnyin kò mọ̀ pé àwọn ti nsáré ìje, gbogbo nwọn ni nsáré nitootọ, ṣùgbọ́n ẹnìkan ni ngba èrè naa? Ẹ sáré bẹ́ẹ̀, ki ẹnyin kí o lè ri gbà. Ati Olukuluku ẹniti nìjàdù ati borí a ma ni iwọntunwọnsi ninu ohun gbogbo. ... Ṣùgbọ́n emi npọ́n ara mi loju, mo si nmu un wá sabẹ itẹriba: pé lẹ́hìn ti mo ti waasu fún àwon ẹlomiran, nítorí ohunkohun, ki emi tikarami maṣe di ẹni ìtanù. 1 Korinti 9:24,25,27.

Lati gbàgbọ́ wípé lẹhìn tí a bá ti di ẹni ìgbàlà pé a kò le sọnù, li lati gbàgbọ́ wípé Ọlọrun ti gba ominira wa tó ga jù kúrò – ominira lati yàn ohun to wù wá. Ní ọ̀nà miran, Ọlọrun fẹ́ kí a mọ̀ dájú pé Oun yio parí iṣẹ́ ti Oun ti bẹ̀rẹ̀ li ayé wa. "Ohun kan yi sa dá mi lójú, pé ẹniti o ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere ninu nyin, yio ṣe àṣepé rẹ̀ títí fi di ọjọ́ Jesu Kristi." Filippi 1:6. A tun lee ní ìgboyà wípé bí a bá tẹ̀síwájú lati maa tẹle E, yi Ó tẹ̀síwájú lati ma tọ́ wa, kò sì ní fí wa sílẹ̀. "Ẹniti ó ba foriti i títí dé òpin, oun naa li a ó gbàlà." Matteu 24:13.

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP5.indd 2 12/6/12 10:42 AM